# IROHIN IMỌLẸ

IMỌLẸ ORẸ AIYE, TẸNI GBOGBO LAWA

No 773 TUESDAY AUGUST 18, 1964 (2D)

## Enia Marun Ku Ninu Ija Igboro

NGOBO :- Laipẹ yi ni Irohin de ọwọ wa pe awọn enia marun ni ẹmi won Ṣegbe ninu ija nla kan to ṣẹlẹ ni Ulam lẹba Ngobo ni ẹkun Tiv ni Ipinlẹ Ariwa ilẹ Naijiria ninu ọsẹ to kọja yi eyi to jẹ pe awọn ọpọlọpọ enia miran lo fi ara gbọgbẹ nibi ija to ṣẹlẹ na, Irohin tun fi ye wa pe ija nla na ko ti dopin bayi ati pe o ti pẹ diẹ ti ọrọ rogbodiyan na ti wa nilẹ.

Irohin na tun fi ye wa pe gbogbo awọn enia to jẹ pe owa ni ilu na lo fi jẹ pe nwọn ti sa kuro fun abala 'ẹmi lori ija na, eyi to jẹ pe ilu kan ti a npe ni Abiade ti o jẹ Ibusọ meje si ilu na ni awọn enia ti salọ bayi lati lọ fi ara pamọ si ilu na.

Agbọrọsọ fun awọn enia ilu na fi ye oniwe Irohin nibiti awọn enia na wa lẹba ile ẹkọ kan ti a npe ni Saint Michael Secondary School Abiade sọ pe awọn janduku to wa gbogun ti awọn enia ilu na bẹrẹ si kọ orin ẹgbẹ Oṣelu kan ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹrinla oṣu yi. Oniwe irohin wa tun fi ye wa pe awọn ọmọ ẹgbẹ Oṣelu na tun fi ina si awọn ile ti o fi jẹ pe ọpọlọpọ ẹru ati ile lo jo patapata. Irohin fi ye wa pe awọn Obinrin ati awọn ọmọde pẹlu awọn enia to fi ẹsẹ rin ibusọ mẹjọ na fun asala ẹmi wọn.

# BENSON JAGUN M'OLU!

## Ireti Lori Iwadi Oloye Benson Fọ Lori Apata !!

UMUAHA:— Rogbodiyan to wa larin ẹgbẹ Alakuko lori eto iwadi ti awọn ọmọ ẹgbẹ na ni yio se lori akitiyan Oloye T. O. S. Benson, Alakoso eto Irohin fun Apapọ Ijọba ilẹ Naijiria ati igba kẹta Olori ẹgbẹ Alakukọ sọ lori apata nigbati awọn ọmọ ẹgbẹ na tun gbe oye wo pe ko si tọna rara lasiko yi a ti ṣe iwadi kan lori akitiyan Oloye Benson rara ninu ẹgbẹ na,

Igbimọ ẹgbẹ Alakukọ ti ilẹ Naijiria tun ṣe alaye ninu irohin to de ọwọ wa labẹlẹ pe ki iṣe ohun to tọ ati eyi to yẹ lati ṣe iwadi kankan gẹgẹbi Igbimọ awọn ọmọ ẹgbẹ na se ro lakọkọ pe awọn yio ṣe ayẹwo lori iwadi Oloye T. O S. Benson nipa akitiyan rẹ ninu ẹgbẹ Alakukọ gẹgẹbi awọn ọmọ ẹgbẹ na ṣe ti ṣe ipinnu tẹlẹ pe nwọn ni lati ṣe eto iwadi ati pe nwọn si ti yan awọn Igbimọ kan ninu awọn Olori ẹgbẹ na lati se eto iwadi na tẹlẹ.

Ninu oṣu to kọja ni awọn Igbimọ ẹgbẹ na yan awọn Igbimọ to ni lati ṣe eto iwadi na lori akitiyan Oloye Benson. Asiko ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ṣe ipade na ni igbati Oloye Benson lọ fun irin ajo kanlati lọ ba wọn ṣe ipade kan ni ilu Cairo.



OLOYE BENSON ATI IYAWO RẸ

### ETO IYIPADA



OLU AKINFOSILẸ

Irohin na fi ye wa labẹlẹ pe ninu ipade kan ti awọn igbimọ ẹgbẹ Alakukọ ti apapọ ile Naijiria ṣe ni Umuaha ni eto iyipada lori iwadi ni awọn ọmọ ẹgbẹ na ti ṣe ipinnu eyiti Olori ẹgbẹ Alakuko ati Alakoso Ijọba Ijọba ipinlẹ Ila Orun ilẹ Naijiria jẹ alaga igbimọ ipade na ni awọn igbimọ na ti ṣe Eto lati fi iwadi na silẹ. Irohin tun fi ye wa pe Oloye T. O. S. Benson ko lọ sibi ipade ti awọn igbimọ ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ṣe ni Umuahia eyiti awọn ọmọ ẹgbẹ na fi ọjọ kan ṣe pade na.

Irohin na tun fi ye wa pe oloye T. O. S Benson ti gbọ labẹlẹ pe ninu ọrọ ti igbimọ ẹgbẹ Alakoso yio sọ ninu ipade na jẹmọ ọrọ lori eto iwadi ti ẹgbẹ na sọ pe awọn yio ṣe lori akitiyan oloye Benson ninu ẹgbẹ na.

Irohin na tun fi ye wa labẹlẹ pe igbimọ apapọ ẹgbẹ na ti fun oloye Benson laye lati sọ ti ẹnu rẹ lori ẹsun ti awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ fi kan lori ihuwa si rẹ ninu ẹgbẹ na nibi ipade ti awọn igbimọ apapọ ẹgbẹ na yio ṣe ni ọjọru ti se ọjọ kẹrindilọgbọn osu yi ni ilu Benin lati le sọ tẹnu rẹ ninu ipade na.

Awọn ọmọ ẹgbẹ Alakukọ ti ṣe eto ijiyan awọn igbimọ kan ti yio ṣe eto lori aṣaro gẹgẹbi awọn ọmọ ẹgbẹ na yio ṣe laseko idibo si ile igbimọ aṣofin ti apapọ Ijọba ilẹ Naijiria eyiti idibo rẹ ni lati waye larin



DR. OKPARA
Olori ẹgbẹ N. C. N. C.

Ọdun yi ati gẹgẹbi ohun ilana ti awọn ọmọ ẹgbẹ na yio mu lo lasiko idibo apapọ na.

WO OJU EWE KẸFA

## E Bu Ọwọ Fun Azikiwe — BENSON

Alakoso eto irohin fun apapọ Ijọba Naijiria ati igbakẹta olori ẹgbẹ Alakukọ Oloye Benson sọ ni owurọ ana ninu ọrọ rẹ lori ọrọ kan ti o wa ninu iwe irohin kan (Daily Sketch) eyiti iwe Irohin na tabuku si arẹ ilẹ Naijiria Ọlọla Dokita Nnamidi Azikiwe.

Oloye Benson tun sọ pe o yẹ ki awọn oniwe irohin le mọ dau ati lati lo ọgbọn ori wọn lori awọn nkan to ṣẹlẹ laipẹ yi lori ọrọ ti iwe Irohin kan kọ jade eyiti o lodi si Arẹ ilẹ Naijiria.

Oloye Benson tun sọ ninu ọrọ rẹ pe ni ilu Gẹẹsi pe awọn enia ilẹ na si bu ọwọ fun Ọba binrin Gẹẹsi gẹgẹbi ẹni ti ko le ṣe aṣise. Oloye *T.* O S. Benson sọ siwaju si i pe awọn oniwe Irohin ati awọn ọmọ ilẹ Naijiria ni lati

Wo Oju Ewe Kẹfa



Dọkita Azikiwe

# AYUNỌRUNBỌ ATI PANPALASO (Apa Kẹrinla)

## AWỌN ỌRẸ AYUNỌRUNBỌ NIWAJU ADAJỌ

LATI ỌWỌ

**J. O. Shoyinka**

Ni nkan bi agogo meji abọ arọ Kotu si kun sọsọsọ ibẹ dakẹ minimini olukuluku wa ninu asọ ala, Gabriel ni agbẹjọro onidajọ ọrun Angeli Micheal ni agbẹjọro awọn Arufin.

Nigbati Onidajọ de gbogbo wọn rọ girigi wọn tẹriba niwaju rẹ lẹhin na ni wọn si joko ẹjọ bẹrẹ awọn ọrẹ Ayunọrunbọ ni nwọn kọkọ pe.

Onidajọ ni ki wọn ka ẹsun wọn si wọn leti nwọn kaa. Angeli G a b r i e l ni, nigbati awọn eleyi wa ni ile wọn ki sin Ọlọrun a fe si lala okiri oko wọn amfi yi ẹjọ pọ wọn ama da ọmọ oruko lori wọn nfi iya jẹ alaini wọn nfi enia rubọ pẹlu, iwa bubuiu wọn ko lonka nitorina kabiyesi adajọ mo da ni imọran pe ki o jẹ wọn si ọgba ẹwọn ẹsu, ki wọn si ma lọ jẹ iya ẹsẹ wọn nibẹ titi aiyeraiye.

Adajọ:- Kini ẹ ni sọ s awọn ẹsun ti nwọn ka si nyin lẹsẹ yi bẹni ori tabi bẹkọ ?

AWỌN ỌRẸ AYUNỌRUNBỌ

Nitọtọ ni ẹsunti wọn ka siwa lẹsẹ ṣugbọn ani alaye.

Kabiyesi Alaiyeluwa, otitọ ni a hu iwa yi nigbati a wa ile, aiye, a ko mọ si aidara, ohun gunmọ li a ro pe a nṣe ni ile aiye nigbana.

A tọrọ idarijin lowọ rẹ Baba Kabiyesi dari ẹsẹ wa ji wa.

ADAJỌ FI ỌRỌ LỌ AWỌN IGBIMỌ

Adajọ feti ko awọn Igbimọ leti, o ni ewo ni ṣiṣe o? Awọn Igbimọ ni ki nwọn da riji wọn Adajọ ra yiju si wọn, o ni mo ro ọrọ nyin sẹhin ori nyin yọ yin pe ẹ tete jẹwọ, ibaṣepe ẹ pero ni oba ju nyin si ọgba ẹwọn Eṣẹ, nibẹ ni ẹ ba ti ma gbadun ninu ina ti o njo lalala ina ajooku

Ṣugbọn nisisiyi ti ẹ ba de ile aiye, a ma tọju iwa yin ẹ ma wọ Ẹgbẹ olukuluku ẹ ma wọ ẹgbẹ Alawo Ọpa ẹ ma lọwọ ninu ipanla, ẹ ẹ ma fi enia rubọ, ẹ ma gbowo abẹtẹlẹ, ki ẹ si fẹ ọmọnikeji nyin gẹgẹbi ara nyin nitoripe on ni Akoja ofin, ẹ fi eyi sọkan ki ẹ si mu lọ ti ẹ ba de le aiye Mo darijin nyin, ẹ ma lọ li alafia, ki alafia Oluwa ti o ju ohun gbogbo lọ, ma ba nyin gbe nwọn fo soke, wọn nyọ ṣẹṣẹ nitoripe Adajọ fi wọn silẹ

Awọn ọrẹ Ayunọrunbọ ṣe sin idupẹ Nigbati adajọ da nwọn silẹ tan pe nwọn ko jẹbi, ki nwọn ma a lọ, nwọn mu ọna ile isin Ọlọrun pọn nwọn lọ nyin Oluwa logo fun oju anu ti o fi wo wọn. Ayunọrunbọ lo ṣẹ iwasu lojọ na ẹsẹ wura rẹ ojọ na ni:-

"Ẹsan ko ni ṣai ke Ẹ tọ ju iwa nyin Nitoripe , ẹsan ko gbogun Ayunọrunbọ bẹresi wasu o ni lilọ ni ẹ nlọ si ile aiye yi ọpọlọpọ ni ohun rere ati ohun buburu ti ẹ ti fi oju nyin ri ati e y i t i ẹ ti ba pade pẹlu, ẹ ri bi ọrun ti ri, ẹ n y i n papa si ti di Ayunọrunbọ pẹlu.

Nisisi ye ẹ o ma pada lọ si ile aiye nitoripe asiko ko iti to ti ẹfi ja wọ ọrun wa lagapanrangbọn, ti ẹ ba de ile aiye ki ẹ ma tan ihinrere O l u w a kale aiye, ẹ ma wasu fọmọ araiye pe i w a ẹṣẹ ko dara, ẹ si mu o f i n m ẹ w ẹ w a wa si wọn leti ẹ ma bikita, ẹ lo miran yio gbọ yio gba, Ọpọlọpọ ni yio ma fi nyin ṣe efe, ẹ ma tiju' nitoripe

'Ọpọlọpọ l a p e ṣugbọn diẹ la o ri' gbogbo awọn ti ẹ ri ni ọrun Apadi ni enia bi ti uyin ni wọn aiṣe dede ni ile aiye lo gbe wọn de inu na ajoku nibiti eṣu lalu oko ti ijọba awọn ti ẹ ba de ile aiye ẹsọ fun awọn ori ẹ upẹ ni o tun npada bọ wa si ile a i y e uhun oni ti wọn yio fi mọ nigbati ọjọ na ba pe, nipe ara yio ma san mananmana yio ma kọ yeriyẹri, yi lile yio si ma ja yio si fẹre wu oku olẹ, ẹ sọ fun wọn wipe ki nwọn maṣe bẹru, emi Ayunọrunbọ Ọkunrin ti a fi nṣepe sọ Ọkunrin li o nbọ yẹn, e teti ki ẹ gbọ ngo kọkọ fara han nyin lori oke ori ẹru ti a ni Aburnkọ nibẹ ni ki ẹ ko ra nyin jo si, nibikibi ti ẹ ba nsọrọ Ọga ogo awọn Angeli o jọko yi nyin ka yi yio ma sọ nyin lọwọ lẹsẹ, nwọn ki o si jẹki npa ọmọ araiye ran nyin Nisisiyi asiko nlọ nko si fẹ gba nyiu laye rara Angeli kan yio mu nyin lọ si ibiti ẹyin o ti yan ipin nyin laiye ẹ farabalẹ ki ẹ yan rẹ nitoripe akunlẹ yan ladayeba.

Ohun kohun ti ẹ ba yan nibẹ li ẹ o jẹ laiye Ibukun Oluwa ti oga ju ohun gbogbo lọ ki o ma ba nyin ba yi ni o si pari rẹ wọn si tuka.

Angeli mu wọn lọ siwaju Akọwe Arun Angeli ṣaju, o dekẹ awọn ọrẹ Ayuuọrunbọ tele nigbati nwọn o fi de ibẹ oti di ọwọ arẹ wọn nwo ilu na lọkankan ti o dabi abọ busọ si ọdọ wọn ẹugbọn oru meji ati oru meji ni wọn fi rin ki wọn to de ibiti kan ti a npe ni Iyi rada nihin ni Angeli mu won wo ibẹ pa ọlọlọ awọn enia pa lọ bi ewerumọ Olukuluku nluwe ninu odo 'IYE, ẹnikẹni to o ba ja lu odo yi ki amọsa yio gbe age enia wọ yio si mura lati mu ọna ajọ rẹ apọn wa sile aiye awọn ọrẹ Ayunọrunbọ e ninu rẹ nwọn da enia pada nihin ti wọu sun si di owurọ ọjọ-keje.

Ni owurọ ọjọ keji Angeli mu wọn losi iwaju akọwe bi Angeli ti kan ilẹkun kokoko ni ilekun ba si ya a wọn si wọlẹ onu wọn duro niwaju akọwe ọrun egbẹgbẹrun ọna ẹgbẹrun enia le wa nibẹ lọkuurin ati lobinrin lọmọde ti lagba wọn duro waiti ṣọja idumata wọn ko gbin pẹn kẹn Angeli si doju kọ awọn ọrẹ Ayinọrunbọ o ni alafia nyin wọn dojubolẹ nwọn ni alafia ni, o ni nisiyi ka ma lọ ngofi nyin sile ni wọn gbbati Ọlọrun ba si nbẹ nẹko ni ri idanu kankan.

Edumare yio si mo siji bo nyin ẹ ma ṣe gbagbe lati tan ihin rere ka ile aiye ti ọwọ ọta bate nyin ẹ pe orukọ Jesu ẹ o si ri igbala.

Ni sisiyi ẹ o ma yan ipin yin ẹ yan dada o nitoripe ou ti ẹ ba yan niwaju Ẹlẹda on na gan ni ẹ o ṣe ni ile aiye ni kukuru odi gba o a o tun pade lẹse Jesu nikẹhin omi le roro loju wọn kia mosa Angeli poora mọ wọu loju.

Ọrọ Igbehin latl ẹnu Akọwe Ọrun


**MODUPE PRINTING PRESS**

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Because Of Their;—*

MODERATE CHARGES
EFFICIENCY
GOOD PRINTING
IMPERISHABLE RECORD
DELIGENT SERVICES
ACCELERATIVE METHOD
PRINTING

*For Your Next Printing Jobs—*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Prnting Press**

**16 Bamgbose Stree**
85, Lagos

# Ikomọ Jade Ibitomirin ko Ni Gbagbe

EKO :- Ọjọ ayọ ni ọjọ ikomọ jade Ọgbẹni Jimọh A. Ibitomirin ẹniti Ọlọrun fi ọmọ kekere Kunmin jojolo kan ta on pẹlu iyawo rẹ Iyaafin Ibitomirin lọrẹ nigbati ilẹ kun ti gbogbo adugbo nọmba 42 Martins Street Eko ko gba awọn alaba ṣẹyẹ aṣeyẹ ikomọ titun na jade ti awọn ẹbi ati ọrẹ si ti ode si ile ẹgbọn Baba ọmọ na lati gbogbo ilu Okere, lagbegbe Eko nigbati ọjọ ikomọ jade na ku ọla.

Ni ọjọ ikomọ na jade gan an ni gbogbo awọn Alufa ti pesẹ si ile ẹgbọn Baba ọmọ na pẹlu adura Orișirişi lati inu iwe mimọ. Lẹhin eyi ni Alufa Taosiri Oke — Imale fun ọmọ titun pa ni oruko lati iwe mimọ eyiti awọn fun ọmọ na ni Bașhiru Ajao. Baba ọmọ titun na ati iya ọmọ na fi jijẹ ati mimu tẹ awọn alataşeyẹ ọjọ na l'ọrun eyi to fi jẹ pe ọpọlọpọ awọn enia to wa sibi ẹyẹ na ẹbagbe lati lọ si ile wọn laseko to yẹ ki awọn kuro nibi ẹyẹ ikomọ titun na jade.

Ọpọlọpọ awọn enia jankanjankan lo wa sibi ẹyẹ ikomọ titun na jade lati Ipinlẹ Iwọ Orun. Eyi ni diẹ ninu awọn enia patakipataki to wa sibi ẹyẹ ki omọ titun jade ni Ọgbẹni Lawal Giwa ti o jẹ ẹgbọn Baba ọmọ titun na, Sule Ọlarohungbe, Lawal ti o jẹ ọrẹ baba ọmọ na, ati awọn ẹgbẹ Anabi to jẹ pe awọn tun şe bẹbẹ si eyẹ ikomọ jade na, awọn ẹgbẹ na ni Disu Giwa, Sule Alaga, Kadiri Akanbi ati awọn miran ti aye ko si lati daruko wọn.

# YE IRAWỌ RE WO

AQUARIUS (Jan 22-Feb 20) Maşe tete yara jẹ ọhẹn tabi ki o maşe tete fi han wipe iwọ nigbẹkele si awọn eni ti ko nifẹ rẹ. Şọra gbogbo iwe ti o ba fẹ kọ laşiri ni ki o kọ.

PISCES (Feb. 21-Mar 20) Maşe fun ara rẹ ni işẹ aşegan, maşe jẹki aiya rẹ ja, nigbati o ba gbọ irohin buruku ẹrin omimi ti o ma orin yẹn, yio şe ọ ni anfani gidigidi.

ARIES (Mar 21-April 20) Nigbati o ba fẹ şe ileri fun enia şọra ki o mọ iru ileri ti iwọ yio şe ki o ma ba ko ara rẹ si yọyọ, maşe fi agbara rẹ torẹ oitori akoko rẹ de tan.

TAURUS (April 21-May 20) Awọn irawọ Ọrun yio şe iranlọwọ fun ọ pupọ. Maşe tete gba gbogbo ọrọ ti ko ni lari ti awọn nsọ fun ọ gbọ, dakẹ ẹnu rẹ maşe ba ẹnikan sọrọ.

GEMINI (May 21-June 21) O vẹ ki o ma ronu wo daradara ki o to şe ohun kan. Tọju ẹnu rẹ ki o ma ba fi ẹnu rẹ daran, şọra lori irin ajo tẹ loni. ere ni iwọ vio je lori ọja ti o ba ta.

CANCER (Juna 22 July 23) Maşe fi ọkan balẹ si iranlọwọ ti awọn ẹlomiran ba şe fun ọ, ki o si şọra nipa ohun ti o oro li ọkan rẹ sa ipa re maşe bẹ ẹlomiran wipe ko ba ọ şe.

LEO (July 22-Aug 22) Ko nşe gbogbo nkan ni yio wa nikawọ rẹ, maşe gba ọrọ akọsọ rẹ gbọ, tabi ohun ti oro li ọkan rẹ maşe fi ore şişe sılẹ, bibẹkọ, iwọ yio lu Ijọgbọn.

VIRGO (Aug 23 Sept 23) Ọrọ akọkọsọ rẹ yio jẹ aşişe ki osi şọra nipa ohun ti o oro ti ọkan fi ikan si işẹ ti o nşe, nibẹ ni ki oje ki emi rẹ wa.

LIBRA (Sept 24-Oct 23 Maşe se ileri kọkan fun ẹnikan loni, ki o ma ba di nkan si ọ lọrun, masi işe mogbogbo ero okan rẹ ni pataki,

SCOPIO (Oct 24-Nov 22) Maşe lala ti ko ni şẹ, ki osi şọ iwa ti o nhu, maşe jẹki eni dabi ọjọ ana fun, akoko o'oro yio jẹ iyara ọtẹ fun,

SAGILTARIUS Nov 23-Deb 21 Aisan le şe ọ loui, odara ki o simi loni maşe jẹki erokero gba ọkan rẹ owurọ ọjọ oni dara fun ọ lọpọlọpọ.

CAPRICORN (Dec 22-Jan 21) Ma wo awọn ẹlomiran bi nwọn ti nşe ki oba le fi şe iwa hu, maşe lo agbara to le pin ara ti awọn ẹlomiran fẹ lo lori rẹ agbara tirẹ ju tiwọn lọ, iwọ yio si bori wọn.

# EGBOGI JEDIJEDI

BERE EGBỌGI



"CYCLOVN"

Aworan ẹgbẹ yi fihan gan lba ibiti Jẹdijẹdi rẹ bi wa ara rẹ si nyọ ọ lẹnu nigba gbogbo. Ibẹ ni a npe ni "omusu tabi iho idi enia ibiti a ma be şe igbọnşẹ Arun Jẹdijẹdi jẹ ọkan ninu amodi ti o buru ni pataki fun ọkunrn ti o si lagbara pupọ lati şe iwosan rẹ patapata.

Ọpọlọpọ egbogi ni nwọn nta kakiri ode nisisiyi ti nwọn ma a polowo wọn un iwosan rẹ şugbọn boya la leri mewa ninu awọn ẹgun ni o le şe iwoşan arun yi daradara, Awọn ẹlomiran lero wipe boya bi wọn ba lọ si ile iwosan lati lọ ke eyiti oba nyọ jade lati omusu ku nipa bẹ awọn o bọ lọwọ rẹ patapata.

Şugbọn awa ko ro bẹ rara lẹhin ọdun diẹ iyọnu rẹ yio si tun bẹrẹ bakana Orisirisi Jẹdijẹdi ni o wa, Ekini ti o bẹrẹ nipa aiko ma şe igbọşẹ dede tabi lojojumọ ẹlomiran nipa ijoko ni ọjokanna pupọ ojojumọ tabi gigun kẹkẹ ologere (Basikulu) pupọ ẹlomiran ẹwẹ fẹran Şuga oniruru ohun adidun pupọ, pupoju nigba kugba Jẹdijẹdi di orisirisi ni o wa, ewo ni tirẹ? Bi o nyọ jade ninu omuşu tabi ti o ba nmu ẹjẹ wa lẹhin igbọnşẹ abi ti o ba nyọ ti o ba şe igbọnşẹ tan ni tabi ti nrin ọ ninu omuşu ni eyikeyi ti o ba jẹ bere egbogi CYCLOVEN ti awọn Oyinbo Jamani şeşẹ wa idi rẹ kio si danwo risi i mẹ a daju wipe iwọ yio bọ lọwọ Jẹdijẹdi patapata alafia lo de ọ ekeji rẹ ko si ninu gbogbo egbogi atata nigboro Naijiria bere ni :

NIGERIAN MEDICENE STORES
Tinubu Square Lagos
4, Adedun Chemist
14, Workeman Street, Yaba


# MODUPE PRINTING PRESS

LEADERS IN MODERN PRINTING
*Firms Patronise* MODUPE PRESS
*Becuase Of Their;—*

- MODERATE CHARGES
- EFFICIENCY
- GOOD PRINTING
- IMPERISHABLE RECORD
- DELIGENT SERVICES
- ACCELERATIVE METHOD PRINTING

*For Your Next Printing Jobs —*
Just Call 21985 - Leave the rest to Modupe
We Guarantee Neat Work And Quick Service

**Modupẹ Prnting Press**

**16 Bamgbose Stree**
Phone 21985, Lagos

